Orilẹ-ede Naijiria

# IWA ỌMỌLUABI ATI ETO ISOTITỌ SI ORILE-EDE

TOGETHER

# ITỌSỌNA YORUBA

Office of the Secretary to the Government of the Federation (OSGF)
Independent Corrupt Practices and Other Related Offences Commission (ICPC)
and
National Orientation Agency (NOA)

ỌFIISI AKỌWE AGBA FUN IJỌBA-APAPỌ
ORILE- EDE NAIJIRIA (OSGF)

AjỌ TI 'N GBOGUN TI IWA JẸGUDUJERA
ATI IWA IBAJẸ (ICPC)

AJỌ ITANIJI SOJUSE ẸNI (NOA)

# IWA ỌMỌLUABI
# ATI ETO ISOTITỌ SI ORILE-EDE

## ITỌSỌNA YORUBA

© Copyright ICPC 2021

*All rights reserved. No part of this publication may be reproduced or transmitted in any form or by any means, electronic or mechanical, including photocopying or otherwise or stored in any retrieval system of any nature, without the written permission of the copyright holder.*

**ISBN:978-978-990-584-3**

Independent Corrupt Practices and Other Related Offences Commission
Plot 802 constitution Avenue,
Zone A9, Central Area,
Abuja.
www.icpc.gov.ng

Independence Corrupt Practices and Other Related Offences Commission was established in 2000 by Act No. 5 of year 2000. Its mandates include enforcement, prevention, public education and enlightenment

# TABILI AWỌN AKOONU



ỌRỌ AKOSỌ - OJU EWE iv

**IPIN KINNI 1** - OJU EWE 1
IFAARA (IBERE)

**IPIN KEJI 2**
KOKO INU IWA ATI ISE FUN ETO IMULO NAA - OJU EWE 3

**IPIN KETA 3**
SISE AMULO ETO ISAKOSO NAA - OJU EWE 8

**IPIN KERIN 4**
IKADI / IPARI - OJU EWE 10

E KAN SI AJO OSGF /ICPC/ NOA - OJU EWE 11



## ORO AKOSO

Aţunse eda tuntun eto imulo Iwa Ọmọluabi ati Isotitọ si Orile-ede ni a tẹ jade nipase Ajọ ti n gbogun ti iwa jẹgudujẹra ati iwa ibajẹ,(ICPC) pẹlu ifọwọsowọpọ ati ajọsepọ Ajọ Itaniji Sojuse ẹni,(NOA) gẹgẹ bi ara akitiyan lati rii pe oye eto imulo iwa ọmọluabi ati isododo si Orile ede ẹni ye gbogbo eniyan/ọmọ orile ede Naijiria yekeyeke ati lati rii wi pe wọn se amulo rẹ.

Niwọn igba ti a ko le fi atunse tuntun yi rọpọ ẹda akọkọ ti igbimọ asejọba apapọ (FEC) fọwọ si ni ọjọ kọkandinlogun, osu kẹjọ, ọdun 2020, ti Aare orile ede wa, Aare Muhamadu Buhari si se ifilọlẹ rẹ ni ojo kejidinlọgbọn, osu kẹsan, ọdun 2020, ni asiko ti wọn se apero apapọ ẹlẹẹkeji lori mimu adinku ba iwa ibajẹ lẹnu iṣe ijoba, ati lati se ajọyọ ogun ọdun ajọ ti n gbogun ti iwa jegudujera ati iwa ibaje. Awọn afoju sun kan waye lati rii wipe wọn se atunse ẹda eto imulo iwa omoluabi ati isododo si orile ede ẹni ni ede ti yoo mu ki o rọrun fun awọn ọmọ orile ede lati ka.

# IPIN KINNI 1

## 1.0 ỌRỌ AKOSO

Agbekalẹ eto imulo iwa ọmọluwabi ati isododo si Orile Ede Naijiria ni a se agbekalẹ rẹ lati ọwọ Ajo ti o ngbogun ti iwa ibaje ati awọn ẹsun to fara pẹẹ (ICPC) pelu ifowosowopo awọn ajo kan ati awon eniyan kan je idahun si orisirisi awon jamba ti iwa jẹgudujẹra fa laarin awọn ile ijoba ati awọn ile iṣe aladani

Agbekalẹ yi waye lati da iwa ọmọluwabi ati otitọ sise pada si awujọ Orile Ede Nigeria.

## 1.1 OFIN ITOSỌNA FUN AGBEKALẸ ETO IMULO YI

Agbekale ofin yi jade lati -

- Iwe ofin Orile Ede Naijiria (1999 Constitution)
- Agbekalẹ ofin Ajọ ti ngbogun ti Iwa ibajẹ ati Awọn ẹsun ti o fara pee (ICPC 2000)
- Agbekalẹ ofin Ajọ itaniji se ojuse ẹni (NOA 2004)
- Agbekalẹ ofin Ajọ Isọkan Awọn Orile Ede Agbaye lati gbogun ti iwa ibajẹ (UNCAC) ati

Afikun lati ọwọ awon Egbẹ bii, Ajọ Agbejoro (NBA); Akoroyin (NUJ), Awọn Ajọ Elerọ onimọ Ero (COREN), Awọn Ajọ Olukọni (TRC) ati bee bee lo.

## 1.2. AWỌN KOKO AGBEKALẸ ETO IMULO YI

Agbekale eto imulo yi ro awọn Ọmọ Orile Ede Naijiria ati gbogbo awon Olugbe Ilẹ Naijiria, tabi awọn alabasisepọ Orile Ede Naijiria lati jẹ Ọmọluwabi, ninu isoroo wọn, iwaa won, ibasepọ laarin ẹnikan si ẹnikeji, ati lẹnu ise fun Isọkan Orile Ede Naijiria.

Riru ofin yi yio fa ijiya to to lati Ile isẹ Ijọba Apapọ ati ti Ijoba Ipinlẹ. A gbọdọ se ẹda, tabi se itunmọ ofin yi ni ilana ti o ba agbekalẹ ofin orile ede Naijiria mu, ati awọn ofin ajọ ti o farạ pẹẹ ki o le to awọn ara ilu ati awọn Ile ise aladani sọna

## 1.3. PATAKI ATI IDI AGBEKALE YI

**Agbekalẹ yi wa lati -**

- Se iranlọwọ fun akitiyan Ijọba nipa mimu iyipada to to ba ihuwasi Ọmọ Orile Ede Naijiria ati gbogbo awọn ti o ni ajọsepọ pelu Orile Ede Naijiria.
- Ran Orile Ede Naijiria lowo lati de ipo idagbasoke gẹgẹbi a se gbe atunse rẹ kalẹ.
- Yọ Orile Ede Naijria kuro ninu koto iwa ibajẹ ti a jin si.
- Lati mu isiri ba awọn Ọmọ Orilẹ Ede Naijiria lati gbe Orilẹ Ede yi laruge ju ẹya tabi ede lo
- Lati ni apero nipa bi a se le da Iwa Ọmọluwabi pada ki Naijiria le ni itẹsiwaju.

**IPIN KEJI 2**

2.0 AWỌN KOKO TO WA NINU ETO ISAKOSO YI.



## 2.1 IBU ỌLA FUN ARA ENI



Eto imulo yi muu daju pe eda eniyan niye lori, a si gbọdọ bọwọ fun, ti a ko si gbọdọ rii fin.

Awọn ohun elo fun ibuọla fun ara ẹni yi ni a ri ninu iwe ofin Naijiria. Ninu eyi ni a ti ri:

1.Eto si igbe aye to wu ni.
2.Ominira lati gbe nibi to wu ni.
3.Ominira lati sọrọ bi eniyan ba ti fẹ.
4.Ominira lati darapọ mọ ẹgbe ti a fẹ.
5.Ominira lati sọ ti inu/t'okan ẹni.
6.Idọgba ni iwaju ofin.
7.Eto si idajọ aisegbe.
8.Ibọwọ fun ara ẹni ati bẹẹ bẹẹ lo

**IMULO**

Ibu ọla fun ara eni ni a gbọdọ gbe sipo to ga ju pe a fẹ jẹ ere ninu igbanisisẹ lọ. Awon eniyan gbọdọ ni enu ọrọ ninu ohunkohun ti o ba kan wọn. Awon eniyan gbudọ ni eto si ipamọ ati asiri ohun tio ba kan wọn. Bakan naa, wọn gbọdọ ri awọn nkan bi Ikorira, Irufin, Ihalẹ, Ijaya, Iyọlẹnu ati wiwa ninu ewu lẹnu isẹ gẹgẹ bi ohun ti ko se ibale ati itẹwọgba fun wọn lenu isẹ.

## 2.2 ISỌRỌ ATI IKOPA.



Isọrọ tumọ si eto lati sọ ọrọ inu ẹni tabi erongba ọkan ẹni, lati le mu ayipada ba awọn ipinnu kan. Nigbati lilowo si/kikopa ninu jẹ ọna kan ti awọn eniyan fi n nipa ninu ise sise tabi isẹlẹ kan.

Agbekalẹ eto imulo yi mu iwuri ba eto awọn eniyan nipa lile sọrọ ati ni kikopa

**AWỌN ISAMULO NINU EYI NI**

Ipile oye isejọba tiwa n tiwa, isejọba to dara, jijẹ awọkose rere, jijẹ asoju, aisi ẹlẹya-mẹya, gbigbo ni lai segbe ati bẹẹ bẹẹ lo.

**IMULO**

Enikọọkan ni o ni eto si ati je asoju ninu eto isejoba, lati le so erongba ọkan ẹni lori ọna ti o ba ye lati se nkan.

Enikọọkan le se afisun iwa ibaje, tabi ohunkohun ti o ba tako agbekale eto imulo iwa omoluabi ati isododo sorile ede ẹni fun eyikeyi ninu awon Ajo ti o n gbogun ti iwa ibaje, tabi fun eyikeyi ninu awon ajo agbofinro, ati pelu, yera fun ọrọ kobakun gbe ati aheso ọrọ ti ko lese nilẹ.

## 2.3 IFẸ SI ORILE EDE ENI.



Ifẹ si orilẹ ede ẹni tumọ si ki a fẹran orilẹ ede ẹni ati pẹlu ifẹ inu ẹni lati daabo boo.
Ifẹ si orile ede eni a maa fun ni ni okun pe a je ọmọ orile ede, ọkun fun iwa isotitọ, isọkan, ifi orile ede ẹni yangan, ibọwọ fun, ifarada, ifarasin, ati bẹẹ bẹ lọ.
Aini ifẹ si orilẹ- ede ẹni ni o maa nse okunfa, iwa aibikita awọn eniyan si ohunkohun to ba duro fun orile ede. Irufẹ awọn iwa ibaje wọnyi ni o a ma n gbile si nibiti ko ba ti si ifẹ fun orilẹ ede eni, iwa bi jegudujera, ailefarada, ẹlẹya-mẹya, ati bẹẹ bẹ lo.
Agbekale eto imulo yi  n fi ojuse ifẹ si orilẹ-ede ẹni han funni.

**IMULO IFE SI ORILE EDE ENI**
Tita asia orilẹ ede Naijiria si gbangba agbegbe gbogbo ile isẹ ijọba.
Pipa ofin mọ, bibọwọ fun etọ ẹnikeji ẹni, ati sisọ ọrọ daradara nipa orilọ ede eni.

## 2.4 OJUSE ENIKỌỌKAN.



Ojuse enikọọkan tumọ si pe ki a ri bi ojuse eni lati wa ọna abayọ si idojukọ laarin akojọpọ awon eniyan kan. Gẹgẹ bi ọmọ Naijiria rere, a ni lati maa se afihan ojuse wa ni igbagbogbo.

**ERONGBA OJUSE ENIKỌỌKAN NI WỌNYI:**
Satunse lori ibaniwi, ibọwọ,  fun itara- ẹni ji, ati ise ara eni ni orile ede lapapo.

Mu ki igbẹkẹle ati igbaralẹ dara si ni ibi ise aladani nipase pipese eto ọrọ aje ati isẹ ti o wa ni ibamu pẹlu osuwọn ti oke okun ni isafihan ojuse ẹni  si awọn ounraja ati awọn agbaso ọrọ miran.

A ma mu igbega ba iye awon ti o ye ki o se asoju ninu eto oselu laarin awọn ti a dibo yan sipo ati awọn ti a yan sipo niti isẹ ijoba.

**IMULO:** Sise afihan ojuse ati ododo ninu sise isẹ ojuse wa. Sisẹ iranlọwọ fun awon ajọ agbofin ro lati riipe a pa ofin ati ase mọ, ati nipa si se afihan owo ati dukia wa fun ajọ agbofinro tio wa nipa yiyẹ eto ọrọ aje wo.

## 2.5 SISO-OTITỌ.



Lati se ohunkohun pelu otito tumo si pe ki eniyan maa se otito nigba gbogbo ni ilana igbekalẹ, ipilẹ oye ohun ti o n dari ohun kan tabi awọn kan pato.

Isotitọ da lori sise ohun ti o to ati sise ohun ti o ba yẹ nigba gbogbo ni agbekalẹ odiwon ti o ni ijerisi ni ibamu pẹlu ohun ti o rọmọ ojuse eni.

Agbekale Iseto imulo naa mu iwuri fun ki ọmọ Naijiria maa se otito.

**Itokasi Apeere awokose Isotito.**

Otitọ: jije olotitọ ati eni ti o se fọkan tan pelu ẹnikeji wa.

**Igboya:** Nini igboya lati le faya ran, idojuko ewu , ibẹru tabi isoro ninu igbe aye eniyan ninu ilepa ati si se rere si orile ede, lai naani ohun ti yoo naa ni.

Ijerisi kan naa: Lati le fọwọ sọya fun ohunkohun ti eniyan ba se ati lati le ni idahun si igbesẹ k'igbesẹ ti eniyan ba gbe lori ibere ki beere ti o ba jeyọ.

**Iberu Olorun:** Gbigbe igbe aye ti o ni iberu Ọlọrun ninu, gege bi atona ninu ibasepo wa pẹlu ọmọnikeji wa.

Awon miran ni Ibowo fun, Imogaara, Ifara-ẹni ji, Ifaraji, Isera ẹni, ati bẹẹ bẹẹ lọ.

## 2.6 ISOKAN ORILE EDE.



Naijiria jẹ orilẹ ede ti o ni ẹya otalenigbadinmẹwa, tio ni orisi ẹsin mẹji, ti o sin ni ẹẹdẹgbẹta ede ati ede abinibi.

O se pataki fun gbogbo ẹya orile ede lati ni iwoye apapo tabi asẹpo paa paa ju lo ni wiwa ni isọkan gẹgẹ bi eniyan ni orilẹ ede ti o lagbara.

Isọkan orile ede tumo si pe ki a ni oye wiwa ni isọkan ni Naijiria gẹgẹ bi orilẹ ede, ati riri pe a je ọmọ Naijiria nibi ti gbogbo ọmọ orilẹ ede ti ni eto kan naa, lai fi ti eya tabi ti orisun se.

Erongba agbekalẹ asa ati ise yi ni lati le je ki gbogbo wa ri ara wa gẹgẹbi okan naa, ati pẹlu, lati jẹ ki a mọ daju pe wọn yoo se asoju ohunkohun ti won ba ni ife si ninu

eto isejoba paapaa ju lo gẹgẹ bi won ti ni eto ati agbara lati le yan ẹnikẹni ti wọn ba fẹ gẹgẹ bi asoju wọn.

**IMULO:** Gbogbo ọmọ orilẹ ede gbudo sisẹ papo lati daabobo isọkan orile ede lati le se aseyori. Yiyago fun iwa jagidijagan ati iwa ipa lati le yanju rogbodiyan tabi aigbọra ẹni ye, biba ara ẹni gbe pẹlu amumora.

**AMULO OFIN:** Enikẹni tabi ẹgbẹkegbẹ ti o ba gbe igbesẹ ti o tako didaabo bo orile ede eni tabi satako isokan orile ede ni o ti se si ofin, ti a o si fi iya jẹ iru ẹni be.

## 2.7 ISE AKODUNJU.



Ise akodunju n tọka si odiwọn giga, to peye ti a n reti, lati odo ẹni ti o ko isẹ kan tabi ohun kan pato. O n'tọka si ifara-ẹni ji tabi ifaramo ipegede isẹ sise, ni ibamu pẹlu agbekalẹ ofin ati ilana ti o ro mọ isẹ akodunju.

**Ofin Ilana.**
Iwe ti o n se atona fun isẹ ijoba, akojọpọ ofin fun osisẹ ijọba, akọjọpọ ofin fun ise akodunju.

**ERONGBA**
Ipegede ni ohun ti a n reti lati ọdọ gbogbo ọmọ orile ede Naijiria ati ni ẹnikọọkan ti o n se idokowo pelu orile ede Naijiria ninu sise ise wọn.

**SISE IMULO**
Iwe Ofin yi mu daju pe gbogbo awọn osisẹ ijọba tabi aladani gbọdọ jẹ ẹniti o kun oju osuwọn, ki o si yago fun sise imẹlẹ, ko si gbodo beere tabi ki o gba ẹbun ẹyikẹyi nipa sise ojuse ninu isẹ ti o n se. Ojuse gbogbo ọmọ orilọ-ede yi ati gbogbo ẹnikẹni ti o n da owo po pelu orilẹ-ede Naijiria ni lati tayọ ninu sise ise wọn gbogbo.

# IPIN KETA 3

## 3.0 IMUSE TI AFIHAN



### 3.1 AKOKO, IMULO ATI ILANA ISẸ

Imulo agbekale yi yio waye ni sisẹ'ntele nipa -

- Pipe gbogbo awon ti o ni iwoye afisun kan naa papo
- Gbigbe eto Ilana ise kalẹ ati akoso rẹ
- Mimu ki agbekale yi wa ni arọwoto awọn eka ijọba yoku (Ijọba Ipinle ati Ijọba ibile).
- Ayọwo igba de igba, amojuto ati sise agbeyẹwo bi isẹ se nlo si.



### 3.2 MIMU OFIN LO ATI IJIYA TI O RO MO

- Ajọ ti o n gbogun ti iwa Ibaje ati awọn ẹsun ti o fara pẹẹ (ICPC) ati awon eka agbofinro miran ni yio se abojuto fifi panpe ofin Ijọba gbe gbogbo awọn ti o ba tapa si ofin yi tabi ti wọn ko lati se amulo rẹ.
- A tun le lo Agbekalẹ yi lati fi gba idajọ ododo.



### 3.3 MIMU AGBEKALE YI LO

- Gbogbo osise ijọba ati aladani ni awọn eka Ijoba Apapọ, Ipinlẹ ati Ibile ni a gba ni imoran lati se amulo Agbekalẹ yi.
- Agbekalẹ yi yio tun wa fun lilo ninu iduna-dura, okowo ibasepo Oro aje ati agboye laarin awọn osisẹ.



### 3.4 AWON ALAKOSO AGBEKALẸ YI

Awọn Ajọ OSGF, ICPC ati NOA; pẹlu atilẹyin awọn Ile ise Ijọba, awọn ẹka isẹ Ijọba ati awon Ile ise Ijọba ni Ipinlẹ ati Ibilẹ ni yio se amulo Agbekalẹ yi.

## IPIN KERIN 4



# LAKOTAN

Idagbasoke eto imulo iwa ọmọluabi ati isotitọ si orileede ọni lati ọwọ Ajọ ti n gbogun ti Iwa Ibajẹ ati awọn akegbe rẹ ati ifowosi fun imulo si awon Agbekalẹ yi jẹ igbese akoni lati mu atunbi ba Orilẹ Ede Naijiria ti yio si tun mun ofintoto ba isejọba wa

Yio tun mu iwoye awọn Ọmọ Orilẹ Ede Nigeria sisẹ fun idagbasokọ Orilẹ Ede yi ati ifẹ ara ati ibọwọ fun omolakẹji wa.

Pẹlu agbekalẹ yi ni mimulo, imọtaraẹni, iwa ipa, aisododo ati aisotito yio di afisẹhin ni Orilẹ Ede Naijiria. Naijiria yio pada bọ si ipo Asiwaju laarin awọn orile ede gbogbo.

**E KAN SI AJO OSGF**
Shehu Shagari Complex, Three Arms Zone, Abuja.
Phone: +234-803-600-1627
Email: info@osgf.gov.ng

## E KAN SI AJO ICPC

INDEPENDENT CORRUPT PRACTICES & OTHER RELATED OFFENCES COMMISSION
ICPC

OLU ILE ISE AJO TI N GBOGUN TI IWA IBAJE ATI AWON ESUN MIRAN TI O FARA PE (ICPC)
Plot 802, Constitution Avenue, Zone A9,
Central Area, PMB 535, Garki, Abuja, Nigeria.
E le fi erongba yin han lori ẹrọ ayelujara ICPC: www.icpc.gov.ng tabi nipa fifi atẹransẹ yin ransẹ si info@icpc.gov.ng (Ajọ ICPC se ileri aabo to peye fun ẹnikẹni ti o ba fi erongba sọwọ si wa).

Ẹ tun le kan si Ajọ ICPC lori awọn ero-ibanisọrọ wọnyii lọfẹ:

- MTN: 08031230280, 08031230281,08031230282
- GLO: 07056990190, 07056990191
- 0800 – CALL – ICPC (08022554272)

E wo ICPC lori ẹro amohun–maworan:
'Corruption Must Go' lori itakun NTA/International ni gbogbo ọjọ-ru ni deede agogo meta aabọ irọlẹ.
E le tẹle Ajọ ICPC lori awọn itakun ayelujara wọnyi:
**Facebook:** www.facebook.com/icpcnigria1
**YouTube:** ICPCNIGERIA
**Twitter:** @ ICPC – PE
**Instagram:** @ ICPCNIGERIA
**Mobile App:** WahalaDey on Android, Windows and IOS phones
**Twitter:** @ ICPC – PE
**Instagram:** @ ICPCNIGERIA
**Mobile App:** WahalaDey on Android, Windows and IOS phones

## E KAN SI AJO NOA

OLU ILE ISE WA WA NI:
Block B, Old Federal Secretariat Complex, PMB 27
Area 1, Garki Abuja, Nigeria.

Bakannaa ni a ni ọfiisi ni gbogbo ipinlẹ mẹrẹẹrindinlogoji pẹlu gbogbo ijọba ibilẹ to wa ni orilẹ-ede wa.
Ẹ pe wa lori ẹro ibanisọrọ: +234-9035928774
E-mail: admin@noa.gov.ng
Website: www.noa.gov.ng
Facebook:
www.facebook.com/nationalorientationagencynigeria
Twitter: @noa-nigeria
Instagram: @noa-nigeria

**Atuntẹ ati atẹjade iwe yi wa lati ọwọ:**
Ajọ ti o n gbogun ti iwa ibajẹ ati awọn ẹsun miran ti o fara pe (ICPC) ati
Ajọ ilaniloye lori eto ijọba apapọ (NOA).
March , 2021.

TOGETHER